## Aworan Onitan

## Lati ọwọ A. O. Ọdunsi, Ibadan




### *Ibikunle file ponti o fi ọdẹdẹ roka*

EKO.

LENULOLOYI ni Oloye Ibikunle Ogungbe ṣe aṣe ni ile rẹ, Agodogba tun awọn ẹbi ati awọn ọrẹ rẹ l'ọkunrin l'obirin ti nwọn wa si Abẹokuta ti nwọn si ba a ṣe eyẹ Oye Asalu Ago Odo, Abẹokuta ti o jẹ ninu oṣu kẹta odun yi. Lẹhin ti Alufa J. Adeyemi ti ṣe adura ti o si ṣe ọrọ apọnle bi Oloye Ogungbe ti ṣe jẹ olufokansin, onitiju ati ọmọluwabi si ni gbogbo aye ni Oloye na ba bẹrẹṣi fi orisirisi onje adidun ati ọti tẹ gbogbo wọn lorun lati owurọ titi di alẹ. Awọn alabaṣeye ojo na le ni igba enia.

Aṣeye ojo na dun o larinrin, Irohin ko to afojuba ni. Oye a mọri o, Oloye Ibikunle Ogungbe.

### David Aina yọ ayọ idominira

ABALABI.

LAIPE yi ni Ọgbẹni David A. Aina yọ ayọ idominira iṣẹ agbẹde-bamubamu (Blacksmith) ti o ti nkọ lati odun ke je sehin. Ọpolọpọ awọn enia pataki-pataki ni o si wa si ibi aṣeyẹ na, bi awọn enia ti pọ to bẹni alaṣeyẹ ominira na si fi jije ati mimu tẹ gbogbo wọn lorun.

### Adajọ ni ki ole "alafebipa" kan lọ ṣe ẹwọn oṣu mẹfa

KADUNA.

NI ojo Aje ti iṣe ojo kejidilogbon oṣu ti o koja yi ni awọn ọlọpa mu ẹsun Okomo Oyo ti o nṣiṣẹ ọna technical work) ni "Kaduna Textile Factory" wa siwaju Malam Bako, Adajọ Kotu Adalu (Mixed Court) pe o ji awọn onise rẹ ni kẹkẹ owu marun. Nigbati Adajọ na ri i pe o jẹbi ẹsun na ni o ba fi dajọ ẹwọn oṣu mẹfa fun un.

Ejọ ti ọdaran na ri ro fun Adajọ na ni pe, ebi ni o nun on jale na. O ni on ti ṣe iṣẹ sọja ri. O ni pọnun mẹrin abọ (£4 10s.) ti awọn "Kaduna Textile Factory" nsan fun on lọṣọṣu ko to o na fun on ati ẹbi on. Ṣugbọ Adajọ na ko gba awawi re ni o ba fi so o si ẹwọn oṣu mẹfa.

# Omugọ l'arun Ọba Ilagida

Lati ọwọ J. Olurebi Williams, Mushin

# Ijẹbu-Imuşin şe Ajọyọ Ajọdun

( Lati ọwọ Isiaq. A. Tokosi )

# Pasitọ Foluwaşayọ ati Oluwafẹmi bẹ Olotu wo


Iwo yio ri i pe ewu rẹ L'OMO JU OMO LOFI FỌ O



OMO ni o NFỌ AṢỌ MỌ JULỌ ni gbogbo agbaiye!










Da IKỌ Ọmọde Duro



DeWitt's BABY COUGH SYRUP





Eniti o mọọ!...

fi MICHELIN TYRES

si bi o ti yẹ

nitoripe awọn ni o dinwo julọ

ti o si ni irọrun julọ

'SDS' fun aye ere sisa ni iwọn iba

'X' fun aye ibiti ere sisa ba yoro

MICHELIN

CFAO - DISTRIBUTORS - SCOA

# Ina edu jo omo odun meji pa

AJA LEBA EKO.

NI ojo Abameta ti ise ojo kerindilogbon osu keje odun yi ni omokunrin kan ti nje Genesis, omo odun meji, omokunrin kansoso na ni Peter Elebe ni, ara ilu Togoland ku sinu ijamba ina edu ni Abule Ikota l'Aja leba Eko.

Baba omo na so fun awon olopa pelu ibanuje ni ojo Isegun ti ise ojo kokandilogbon osu na pe bayi ni omo on na se ku sinu ina ti Tiamiyu Sule ti awon jijo ngbe Abule kanna da ti o fi nsun igi di edu, o si se alaye pe bi nwon ba fe se edu, nwon a to awon igi idana jo ga si oke bi atibaba kekere, nwon a ko ew ati iyanrin bo o, nwon a si dana si i labe. Ina na yio ma a jo titi ti awon igi ibe yio fi di edu patapata.

Elebe ni lehinti Tiamiyu ti se eto igi yi tan lojo na ti o si ti dana si ilabe tan ni o ba lo si osa lo se nkan miran. O ni bi o ti lo si osa tan ni omo on na ba gun oke igi na pelu aimokan, o si lo joko lori re, o nsere. Lojiji ni oke igi na wo pelu omo na si isale ninu ina, ni ina ba jo omo on na pa ki awon to yo o, ni awon ba gbe oku re lo si lakuiaku ni Ile-iwosan Ijoba.

Awon olopa wa lenu iwadi bi omo na ti se ku.

# Ore kan se ore re l'ese nibi ariya isinku, o w'ewon osu mejidilogun

ABEOKUTA.

NI ojo Aiku ti ise ojo kefa osu ti o koja yi ni awon ore meji kan Nuraini Aremu ati Yekini Alade lo si ibi aseye isinku kan ni ilu yi nwon si jijo joko papo larin awujo awon alabaseye yoku. Nigbati ero ti po dada, nwon si fi onje te won lorun. Lehin eyi, nwon ha oti fun won, gbogbo won si ngmu oti, nwon nse faaji.

Enu oti mimu yi ni nwon wa ti ito fi gbon Yekini Alade, o si dide lati lo to sugbon ore re Nuraini Aremu di i mu pe ko gbodo lo ayafi ti o ba gba ase lenu alaga ijoko na. "Jeki nlo—o ko ni lo" ni ija ba fi de. Bi nwon ti nja ija yi lo ni Nuraini Aremu ba fi obe alafefe ya Yekini Alade ni eje ba ru jade.

Nigbati awon olopa ro ejo yi fun Adajo Kotu Ake "Ake Grade 'A' Court" l'Abeokuta ni ojo Abameta ti ise ojo kerindilogbon osu yi, ti Adajo na si bi odaran na bi o jebi tabi ko jebi, ejo ti o ro nipe, on ko fi oba alafefe ya ore on, aga ti awon o fi ba ara won ja ni o da ogbe si i lara. Bi odaran na ti ro ejo yi tan, Adajo na ni, iwa buburu gba a ni eyi ni o ba so odaran na sewon osu mejidinlogun.

# Adegoke gbe Moriamo ni iyawo

NIAMEY NIGER F.W.A.

NI ojo Ojobo ti ise ojo kokanle osu kefa odun yi ni Ogbeni Shittu Adegoke gbe Omidan Moriamo ni iyawo alarinrin. Nigbati ojo igbeyawo na ti ku ola ni ese gbogbo awon enia pataki-pataki ati awon gbajumo ti peju sibe ti nwon si ba won se aisun eye igbeyawo na moju.

Bi awon enia ti po to nibi aseye igbeyawo na ni baba ati iya oko-iyawo pelu awon ebi won fi orisirisi onje adidun ati orisirisi oti te won lorun. Beni awon onilu nfi kokoro-ilu won dara ti awon alabaseye paapa si nfi idunnu la ijo mo'ra titi ti ile ojo na fi su. Irohin ko to amojuba ni eye igbeyawo na, o bu-aiya o le gongo.

Awon die ti aye wa fun lati ko oruko won ninu awon alabaseye na ni Ogbeni Fasasi Akande, Asimi Akano, Alfa Fasasi, B. A. Hasiru, Alhaji Salau, D. A. Adejumobi, T. A. Aremu, Asiru Oyebisi, Shittu Telo, Rabiu Akanni, Salawu-Ajagbe, Saka Akinbi ati Alimi Isola. Ki Oluwa fi rere kari o.

# St. Abrio s'eye fun Olowa ati Ajayi

(Lati oju ewe karun)

Kowe si Oloye S. L. Akintola Minista Alamojuto Eto Ise Waya ati ti Oko Ofurufu Apapo Ijoba Naijiria ki o ba won se eto a ti tete ri telifonu gba ni Mushin.

Nwon si ki Ogbeni Ajayi ti yio ropo re nwon si so fun un pe yio dun mo awon papo ti o ba le tele apere iwa rere ti Ogbeni Olowa fi mba won lo fun gbogbo igba yio fi sise ni arin awon, Ogbeni Ajayi na si dupe lowo won, o si se ileri a ti ma a se dada pelu won. Ogbeni St. Abrio si fi jije ati mimu te gbogbo won lorun. Ogbeni E. A. Cole ni o fi adura Ore-ofe pari ipade aseye na. Die ti aye wa fun lati daruko ninu awon alabaseye na ni awon Ogbeni Akintola Cole, Fred Adeyegbe, D. O. Odutola, V. A. Cole, S. K. Omaigbe. Kansilo Lawani O. Oluwo, J. Ayo Nuga, E. A. Coker, T. A. Lawani ati Iyaafin Olowa.

# Egbe Oredegbe sere Ajodun Ileya

### (Egipeleke ni ere na)

NI ojo Isegun ti ise ojo kini osu keje odun yi ni awon Egbe Oredegbe ilu yi jo Ijo Ajodun Ileya, nigbati are na ti ku ola ni gbogbo awon omo egbe na ti peju si ile Ogbeni Shittu Akanbi Lawani, Babaegbe won, nwon si se aisun moju kendenren. Nwon si fi gbogb aro ojo na simi are aisun ti nwon ti se, sugbon nwon nje nwon si ngmu, nwon nba orisirisi onje ati oti fun gbogbo awon alabaseye won titi osan.

Nigbati o di irole ti nwon ti jo yi'lu po tan ni nwon wa lo pa agbo-ijo si gbangba oja-atijo pelu awon alabaseye won, ero iworan dabi omi, bi awon omo egbe ti nfi ijo dabira ninu agbo ti awon onilu paapa si nfi ilu pa orisirisi owe ati ko orisirisi orin, ni awon ti o wa lehin agbo paapa njo lo bi-ile-bi-eni, ti ariwo nta ge e ! ti kakaki ndun bi igbati a wipe afin-oba ni nwon ti nfon on. Awon Ashanti l'okunri l'obirin ti nwon gbo ede Yoruba bere si jo lo bi-ile-bi-eni lehin agbo. Irohin ko to afojuba ni. "Eyi-peleke" ni gbogbo awon enia npe irohin ijo na.

Oruko die ninu awon egbe na ni Sariyu Awero (Iyaegbe); Wule Abeke, Tawa Akanke, Ola Aweni, Amudatu Arinpe, Safu Asunke, Aminatu Arike, Fuleratu Asake, Sala Arike, Limota Abeke, Belau Abake, Raji Alake, Saratu Awele, Aminatu Asabi, Salamotu Arinpe ati Abiba Abike. Awon alabaseye ti o ko egbe tiwon wa si ibi aseye na ni Bello Areo, Aminu Olaribigbe ati Karimu Akano. Awon amulegbe Baba-egbe ti nwon jijo wo aso iru kanna ni awon Ogbeni Samuel Fadiji, Isaac Adebisi, Oyeniyi ati Jacob Ola, Abatan.

Aseyi-samodun o.


# BI O BA FI KEROSINI SHELL TA'NA




ORU YIO DABI OSAN

# Ijẹbu-Imuṣin ṣ'ajọyọ ọdun

unti oju ewe keje

(Health Sister) ni Ijẹbu-Ode. O si pin ẹbun fun awọn ọmọ-ọwọ ti nwọn ni agbarajlu ti nwọn si ni imọtoto ju awọn ọmọ-ẹgbẹ wọn yoku lọ. Lara awọn ọmọ ti o gb'ẹbun na ni Abiodun Oṣikoya, Taiwo ati Kehinde Jaiyeola, Isiaq Muse Oliwolimo, Busura Disu ati Omolade.

Lẹhin eyi ni awọn ọmọ ile-iwe lo yika ọdan ti nwọn ti ṣe akọrin ìdile, ere na dun pupọ. Bi nwọn ti pari eyi tan ni awọn ọmọ Ẹgbẹ Ibilẹ Ijẹbu-Imuṣin ẹka t'Eko Tọkunrin Tobirin bẹrẹ ijo pẹlu orin aladun, gbogbo wọn si wọ aṣọ ẹgbẹjọda kanna. Ere na dun to bẹẹ gẹẹ ti o fi jẹ pe ohun ni nwọn ṣe titi ilẹ fi ṣu.

Lẹhin eyi ni nwọn dari lọ si Gbongan apejọ St. Mary School nibiti awọn diẹ kan gbe lọ ṣe ere idaraya itan "Ẹru kan ti o di Ọba" ti Ọba ti o ti ra a lẹru ti o si ti lo o ni ilokulo tun pada wa di enill o nwari fun nitori ipo ọba ti ẹru na ju tire lọ gẹgẹbi eto isẹdale, lẹhin eyi nwọn si fi ijo Abalabi pari aṣeyẹ ti ọjọ na.

Nigbati o di ọjọ kẹta ti nwọn ti bẹrẹ ajọyọ ajọdun na, ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹta oṣu yi kanna, gbogbo wọn si lọ si Ile Isin ti o wa ni adugbo olukaluku nibẹ ni nwọn gbe ṣe akanṣe isin idupẹ fun ipari eto ajọyọ ajọdun na. Oro igbiyanju ti awọn Alufa Ṣọọṣi wonyi fi gba awọn alajọyọ na ni iyanju ni wipe "Ninu isowọpọ ni agbara wa". Nwọn si pari ajọdun na pẹlu akanṣe adura.

Diẹ ninu awọn enia pataki pataki ti o wa nibi aṣeyẹ ajọdun na ni Alaiyeluwa Ọba Adetayo Kini, Orimolusi Ijẹbu-Igbo, Ọba Adeboyejo Keji, Oloko Ijẹbu-Imuṣin, Iyaafin Adeola Odutola, Iyawo Ọgbẹni Ọla Ijẹbu-Ode; Ọgbẹni Buraimo Oliwolimo, Imam Agba; Alfa Muse Ade Sule, Ọgbẹni A. O. Igbodipe, Oloye A. O. Orẹsanya, Oloye Iyaafin Igbodipe, Ọgbẹni Isaiah Adigboluja, Alfa Muse Sule Oliwolimo ati Ọgbẹni E. S. Onatola.

Aṣẹyi-samọdun o.



Aworan oke yi ni ti igbati Ọgbẹni Allan Lennox-Boyd, Aṣoju Ijọba Gẹẹsi f'awọn Ilu Abẹ Ijọba Gẹẹsi mba awọn Oseiu Arinrin-ajo Naijiria ti Ọgbẹni J. G. Adeniran je okan ninu won jiroro ninu yara Ile-iṣẹ re ni Ile Igbimọ Apapọ Ijọba Gẹẹsi (House of Commons). Awọn ti o joko ni Malam Mutari Sarkin Bai, Oloye O. Oweh, (Asiwaju awa arinrin-ajo na) Ọgbẹni Lennox Boyd, Aṣoju Ijọba Gẹẹsi fun awọn Ilu Abẹ Ijọba Gẹẹsi), Ọgbẹni D. C. Ugwu ati Ọgbẹni L. S. Fonka. Awọn ti o duro ni Malam Hassan Yola, Ọgbẹni S. O. Onabolu (Akọwe Irin-ajo wa), Ọgbẹni J. C. Obande, Ọgbẹni J. G. Adeniran, Ọgbẹni Peter Smithers (Aṣoju Winchester ninu Ile Aṣofin Gẹẹsi) ati Ọgbẹni J. S. Taika.




## Adedeji ṣe ọjọ ibi rẹ

Ọyọ.

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ keji oṣu yi ni Ọgbẹni Jonathan A. Adedeji ti nṣiṣẹ ni ile iṣẹ ohun ọgbin "Agricultural Department Fashola" l'Ọyọ, ṣe ajọdun ọdun ketalelogun ti a bi i. Ẹsẹ ọpọlọpọ awọn gbajumọ ni o ṣe aibẹ.

Diẹ ninu awọn alabaseye ọjọbi na ni awọn Ọgbẹni Samuel Fameshe, Yesufu Olayiwola, Saka Adeleke, Hezekiah Ayoade Tafa Ladeji, Kayode Fameshe, Joseph Kolawole ati Salawu Onilu.

Ki Olorun jeki o ṣe ọpọ ọdun laiye o.

## Moto kan kolu igi, o pa ọkunrin kan l'Eko

EKO.

NI ọjọ 'Ku ti iṣe ọjọ kefa oṣu yi ni ọkunrin kan ti o njẹ T. K. Agbonmagbẹ, ti o nṣiṣẹ ni Ile-iṣẹ "J. Allen and Company" l'Eko ku lẹsẹkẹsẹ nigbati moto rẹ kolu igi nla kan ni ọjude Ile-iwe "St. Mary's School" ni Opopo Broad Street, Eko. Iyawo kan ati ọmọ mẹrin ni Ọgbẹni T. K. Agbonmagbọn fi s'aiye lọ.






# Ajọdun Tabborra

A fẹ ki o di mimo fun gbogbo enia pe Ajọdun Taborra ti a nṣe ni ọdọdun ni Ogere Headquarter, Ijẹbu-Rẹmọ, Via Shagamu yio wa ni alẹ ọjọ Eti (Friday) ni ọjọ kejilelogun oṣu August (22nd August, 1958) bi a ti nṣe ni ọdọdun. Eyiti gbogbo enia wa ngba Ore-ọfẹ ni ọdọdun gẹgẹbi ti akoko ti awọn ọmọ Israeli ti gbogbo enia si nma goke lọ si Silo lati gba ire odun; bẹni ẹnikẹni ti o ba fi igbagbọ ati okan Mimọ gun Ori Oke yi yio ri ire tirẹ gba ni oniruru ona ti olukuluku nfẹ ire si.

Alafia fun nyin.

**Dr. J. O. Ọshitẹlu**

Psy.D. The Primate & Founder.

# Ina ti nwọn da sile fun otutu pa tọkọ-taya

KAFANCHAN.

LẸNULỌLỌYI ni ọkunrin kan ti o njẹ Aginde, ẹni ọdun mẹdogbọn ati iyawo rẹ Nza, ẹni ọdun mọkanlelogun ti nwọn ngbe inu ile kan ni Jema jona-ku sile nigbati ina ti nwọn da sinu ile fun otutu gbina mọ'le loganjọ oru. Nwọn si ti ko oku wọn lọ si Lakulaku Ile-iwosan nla fun ayẹwo. Nwọn tun gbe oku ọkunrin kan ti nwọn ko mọ orukọ rẹ wa si Lakulaku na ni ọjọ kanna, oko Reluwe ti o nti Jos lo si Kuru ni o tẹ e pa nigbati o fẹ pada wọko lẹhin ti o ti sọkalẹ.

## *Pa-Joaquim*

(Lati oju ewe kini)

O ni lati igbati Dokita Nnamdi Azikiwe ti nṣe Olori Adapo-Ẹgbẹ Demọ mọ Ẹgbẹ Alakuko yi ni ko ti si eto iṣelu tabi eto ẹgbe ti o gun rege mọ, ila, aigbọran, ifẹ-imotara-eni-nikan, ainifẹ-ara ilu lokan, yiyọni ni ẹgbẹ lainidi ati orisirisi iwa aidara gbogbo ti o nti enia loju ti ko ye ki a ma a ba awọn ọmoluwab ni idi rẹ ni nṣelẹ nigbagbogbo. O ni on rọ gbogbo awọn Ẹgbẹ Ọloja Obirin ki nwọn tete yera fun Ẹgbẹ Alakuko Ọgbẹni Joaquim na, ẹni ọdun marundinlogorin ti iṣe Olori Ẹgbẹ "Nigerian National Democratic Party" si ti wọ Ẹgbẹ "Democratic Party of Nigeria and Cameroon" ti Dọkita K. O. Mbadiwe ṣẹṣẹ da silẹ.

# Laja ati Ligali w'ẹwọn

Lati oju ewe kini

da a pada. O ni awọn ọlọpa ni yio ṣe idajọ eyi ṣa.

Bi Adajọ na ti dajọ wọn tan ti nwọn si ko wọn sinu moto ẹlẹwọn kan ti wọn wa wọn lọ s'ọgba ẹwọn ni Broad Street ni ariwo ẹkun gbojikan ni ita kotu na: awọn iyawo awọn ọdaran na, awọn ọmọ wọn ati awọn ẹbi wọn nsọkun, nwọn si ngbe ara sọnlẹ. Ọkẹ aimọye enia ni o pe si ita kotu na ti o nwo iran wọn lọjọ na.

# Ọjọ idominira

Lati oju ewe kini

awọn ti o sọrọ iwuri si imọran na. Gbogbo wọn si gba bẹ e, nwọn si ṣe ipinnu le e lori.

### AWOLỌWỌ GBA IYI NI ILE IGBIMỌ APAPỌ IJỌBA NAIJIRIA

Bi ogunlọgọ awọn enia pataki pataki ati awọn mẹkunnu ti nwọn wa woran bi awọn Aṣoju Naijiria ti ṣe nṣe apero na lọjọ na ti ri Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ; Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria lọọkan ti o mbọ wa woran ninu Ile Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria bi nwọn ti ṣe nṣe eto Igbimọ na si ni nwọn ti bẹrẹsi yọmbọ rẹ titi o fi wọle, ti nwọn nlogun "Awo! Awo!! Awo!!!" l'ọtun l'osi. Oloye na si bẹrẹsi juwọ si wọn pẹlu idunnu. Bẹẹna ni nwọn si tun ṣe fun un nigbati o jade kuro ninu Ile Igbimọ na. Oloye na jẹ alejo ti o pataki julọ ninu awọn alejo ti o wa woran awọn Aṣoju Igbimọ ni ọjọ na.









Printed and published by the Amalgamated Press (of Nigeria) Ltd., 5/7, Apongbon Street, Lagos. (Editorial and Advert offices). Telephone 23875. Fun owo "Irohin Yoruba" odun kan: Eko—sile mejo ati kobo mejọ (8s 8d.). Ilu miran ni Naijiria ati Oke-Okun—sile metala (13s.). Olotu S. M. Ademuyiwa, 9, Chapel Street, Lagos.